**Ijọ́ Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu**
**Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàìjíríà**
**ÌSÌN OMI MÁNNÀ**
**Kókó Àdúrà – ÌWÒSÀN PÍPÉ (9)**

**Ìjẹ́wọ́: Jeremíàh 30:17: Nítorí èmi Ó fi ọ̀já ìmúláradá lé ọ, èmi Ó sì wo ọgbẹ́ rẹ sàn, li Olúwa wí; nítorí nwọ́n pè ọ́ lí ẹnití a lé jáde; Síónì, tí ẹnìkan kò ṣàfẹ́rí rẹ.**

**Orin Ìyìn àti Ìjọ́sìn**

1. Gbogbo ojú àjẹ́ tó n kó àyídáyidà bá àláfíà mi, di gígé dànù, ní orúkọ Jésù.
2. Olúwa, jẹ́ kí ojú àwọn àgbà ìkà tó nkó àyídáyidà bá ayànmọ́ mi di yíyọ jáde nípa iná, ní orúkọ Jésù.
3. Ọfà iná, yọ́ gbogbo ojú àwọn ìránṣẹ́ tó n tọpinpin lórí ọ̀rọ̀ ayé mi, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo agbára òkùnkùn tí ó di ẹran-ara mi mú, tusílẹ̀ báyìí, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
5. Bí ẹja ṣe pọ Jónà sórí ilẹ̀ gbígbẹ, agbára òkùnkùn ìyówù tí ó ti gbé ayànmọ́ mi mìn, pọ̀ ọ́ báyìí, ní orúkọ Jésù.
6. Agbègbè ayé mi ìyówù tí àwọn ẹ̀mí ọlọ́tẹ̀ ti gbé mìn, di pípọ̀ jáde, ní orúkọ Jésù.
7. Agbára ìkà ìyówù, tí ó ti gbe ìlera mi mìn, pọ̀ ọ́ jáde báyìí, ní orúkọ Jésù.
8. Mo fò jáde kúrò nínú àwọn òbí mi, ẹ̀yin òbí mi, ẹ fò jáde kúrò nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
9. Gbogbo iṣẹ́ iṣìnkú àjẹ́ lórí ayé mi, tó n yọ ìlera mi lẹ́nu, gba ìfagilé báyìí, ní orúkọ Jésù.

10. Gbogbo iṣìnkú àjẹ́ tó lòdì sí ìlera mi, gba ìfagilé báyìí, ní orúkọ Jésù.
11. Ìlera mi tí wọ́n gbésin sínú ìgbé-ayé òkùnkùn, gba ìtúsílẹ̀ báyìí, ní orúkọ Jésù.
12. Olúwa, túmisílẹ̀ kúrò lọ́wọ́ ṣẹkẹ́ṣẹkẹ̀ ìrandíran, tí wọ́n ṣe lòdì sí ìlera mi, ní orúkọ Jésù.
13. Ọ̀pá sátánì tí wọ́n yàn lòdì sí ohunrere nínú ìdílé mi, yangbẹ, ní orúkọ Jésù.
14. Mo kọ gbogbo ìmísí àjẹ́ lórí àláfíà mi, ní orúkọ Jésù.
15. Mo kọ gbogbo àjogúnbá ibi ìrandíran, ní orúkọ Jésù.
16. Gbogbo ìjọba òkùnkùn nínú ìdílé mi, mo pa ọ́ run nípa iná, ní orúkọ Jésù.
17. Mo kọ̀ láti ṣiṣẹ́ lábẹ́ ìjẹgàba ibi, ní orúkọ Jésù.
18. Olúwa, jẹ́ kí àrá àti iná ṣàwárí fún ìparun pátápátá, gbogbo àjọ àwọn àjẹ́ àti oṣó, tí wọ́n gbékalẹ̀ lòdì sí mi, ní orúkọ Jésù.
19. Bí fìtílà tí n yọ́ níwájú iná, jẹ́ kí gbogbo àjọ àjẹ́ ti ó fi ayànmọ́ mi sínú àhámọ́ pòórá nípa iná, ní orúkọ Jésù.
20. Gbogbo ilé ìfowópamọ́-sí àti yàrá agbára òkùnkùn, tí ìlera mi mbẹ nínú rẹ, di fífà lulẹ̀ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
21. Olúwa Ọlọ́run mi, jẹ́ kí iná Rẹ sọ̀kalẹ̀, kí ó sì jórun gbogbo àpéjọpọ̀ ibi tó n mú ìjákulẹ̀ bá ètò Ọlọ́run fún ayé mi, ní orúkọ Jésù.